Bibeli fun awon omode



# Idasile Ijo

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.



Nigba ti Jesu ku, eru mu awon omo eyin re won si fi ara pamo. Leyin ajinde, Jesu kuro ninu oku o fi ara re han fun awon omo eyin re. Jesu wa laaye i sugbon Jesu ni lati fi won sile lo si orun ni ibi ti o ti n gbe pelu Olorun tii se baba re.



Ki o to lo Jesu se ileri fun awon omo eyin re pe Oun yoo ran emi mimo Olorun si won lati maa se Olutunu ati Oluranlowo won (Johanu ori Keedogun ese kerindinlogun). Akoko naa sun mo! leyin ojo die ti Jesu ti lo, emi mimo Olorun Sokale wa.

Bayii ni o se sele. Nnkan bi ogofa omo eyin Jesu kora won jopo sinu ile kan ti won si n gbadura. Ni ojiji ni inu ile naa kun fun iro efuufu lile.



Ni ela ina pin ara re si ori eni kookan, ti gbogbo won si kun fun emi mimo gege bi Jesu ti se ileri.



Awon omo eyin Jesu n fi ede tuntun ti won ko so ri soro ni opopona. Awon ajeji ti won gbe Jerusalemu wo n gbo ti awon omo eyin naa n royin ise iyanu Olorun pelu oniruuru ede. Enu ya awon ajeji naa won n bi ara won pe iru kin ni a o wa tumo nnkan wonyi si, "won wa mu oti yo ni" ti won si n fi won se eleya.



Peteru so pe “Won ko mu oti, Eyi ni asotele wolii Joeli, Peteru wa mu un wa si Tiranti won pe, Ni Odun die seyin ni Olorun ti se ileri pe oun o ran emi mimo. Oun wa se ibukun ati iranwo fun awon eniyan”.



Peteru so fun awon eniyan pe won gbodo yipada kuro ninu ese won ki a si Baptisi won ni oruko Jesu Kristi. E o si gba ebun emi mimo. Peteru so pe. Nnkan bi egbaakan aabo (3000) eniyan ni won gbo ti won si darapo mo awon omo eyin gege bi olujosin Jesu. Bi ojo se n gori ojo ni a tun n yan awon eniyan kun ijo Olorun lati igba ti emi mimo ti sokale.



Emi mimo gbe agbara re wo
inu aye awon eniyan Olorun.
Ni ojo kan Peteru ati Johanu
goke lo si tempili ni wakati
adura.  Okunrin alagbe kan
jokoo ni enu ona abawole
tempili.  On toro owo lowo
Peteru ati Johanu.





Peteru so pe wura ati fadaka Emi ko ni sugbon ohun ti a ni ni pe, ni oruko Jesu Kristi ti Nasareti dide ki o si maa rin O si fa a ni owo otun re soke.  Bee ni o dide o naro o si n rin, o si wo inu tempili pelu won. O n rin o n fo, o si n yin Olorun.

Opo eniyan pejo, enu ya won si ise iyanu naa, Peteru wi fun won pe agbara Olorun ni kii se ti oun ni o mu okunrin aro naa ni ara da.  Nigba to peteru ran awon



juu to wa nibe leti pe Olorun ti ji Jesu kuro ninu oku.  Awon olori ninu tempili fi ibinu ju Peteru ati Johanu sinu tubu.  Sibe nnkan bi egbaa meji aabo tun gbagbo ninu Jesu si.

Ni ojo keji Peteru ati Johanu duro niwaju awon alase tempili; ti won si n bi won leere pe nipa agbara tabi oruko wo ni eyin fi n se nnkan wonyi? Peteru si kun fun emi mimo on fi igboya dahun pe "Nipa oruko Jesu Krisit ti Nasareti ni eni ti e kan mo agbelebu, ti Olorun si ji dide kuro ninu oku nipase re ni okunrin yii duro niwaju gbogbo yin."





Peteru n tewaju si laifoya, ko si oruko kan ti a fi fun eniyanni abe orun ninu eyi to a fi le gba wa la. Awon alase wonyi ko de fe ki awon eniyan o tun gbagbo ninu Jesu. Won situn n kilo fun Peteru ati Johanu pe won ko tun gbodo waasu fun eni Kankan mo ni oruko Jesu.



Peteru ti n beru tele lati soro ni oruko Jesu sugbon igba yen je igba tiemi mimo ko ti de Nibayi won ko beru enikan kan mo. Peteru ati Johanu dahun pe. N je O ha to ni oju yin lati gbo tiyin tabi ti Olorun, e wi fun wa tori awa ko le ma a so ohun ti a ti gbo ti a si ti ri.

Leyin opo idun kooko mo ni, Awon alase tu Peteru ati Johanu sile. Awon olusin Olorun ba ara won soro, won si korajo papo lori gbongan idajo ati ewon. Won n fi itara gbadura won si n yin Olorun. Emi mimo Olorun tori kun inu awon eniyan re pelu agbara ijo kekere si n teswaju ati siwaju si i.



Idasile Ijo

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ise awon Aposteli Orukin-in-ni
titi de ori kerin

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.